Bibeli fun awon omode

# Jeremaya, Okunrin Elekun



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Jonathan Hay
Alastair Paterson

Olu'lo: Mary-Anne S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

A bi Jeremaya si idile onigbagbo ni igba isejoba Juda. Baba re, Hilkaya, je wolii. Idile naa n gbe ni ilu ti a n pe ni Anatoti, ti ko jinna si Jerusalemu. Boya awon obi Jeremaya ro pe oun naa yoo di wolii. Sugbon Olorun ni eeto miiran.



Nigba ti a bi Jeremaya, awon eniyan Olorun ko gbe gege bi oro Olorun. O fere e je gbogbo eniyan lati ori Oba titi de ori Osise ti o kere julo, ni won nsin Olorun eke – koda ninu Tempili mimo Olorun!





Nigbati Jeremaya wa lomode, Olorun baa soro. “Mo ti mo o ki a too bi o” Olorun so fun Jeremaya, ati pe Emi palemo nigba naa pe iwo yio jise fun mi.

Ipe Olorun ba Jeremaya leru. “Ah, Oluwa OLORUN! O kigbe soke. Emi ko le soro, nitori omode ni ni.” O ti ju omode lo – omo ogun odun ni, sugbon Jeremaya ko ro pe oun le soro jade fun Olorun laarin awosn ika eniyan larin ayika re.



"Ma beru", Olorun fun Jeremaya ni idaniloju, "Lo si ibikibi ti Emi o ran O. So ohunkohun ti mo ba so fun O."



"Emi wa pelu re ati pe Emi o gba O." Nigba naa Olorun se ohun ara oto. Olorun fowokan Jeremaya lenu.

Olorun fun Jeremaya ni Okun, imul'okanle ati Ogbon. O soro pelu igboya, o ran awon eniyan leti pe Olorun feran won a tipe o fe lati ran won lowo. Sugbon ko si eniti o teti sile sii, koda to fi mo Oba.



Koda awon alufaa n binu, won si wi fun un pe ki o dake lati maa soro nipa Olorun mo Opo awon woli eke ni won so pe Jeremaya ko so otito.



Jeremaya ran awon eniyan naa leti pe, nnkan bi ogorun odun seyin, ijoba Ariwa Isireli ti ko Olorun sile. Awon ota won, Asariya, segun won, won si ko won lo si ile ajeji.





Nisinsinyi awon eniyan Juda, ijoba Gusu, ti ko Olorun sile.  Awon ota ologun ti wa loju ise.  Se Olorun O gba ki awon ota bori awon eniyan re?  ki won simu won lo si igbekun pelu?

Awon eniyan naa gbagbo ninu orisa, se orisa le gba won kuro lowo awon ota? Rara! Olorun nikan lo le gba won. Awon eniyan naa binu gidigidi si Jeremaya, won gbimo lati pa a sugbon Olorun daabobo Iranse Re.



Nigbeyin, Olorun so ohun kan ti yio ba jeremaya leru, Olorun wi pe "Ma gbadura fun awon eniyan naa mo.  Emi konii gbo won nigba ti won ba sunkun fun iranlowo."



Jeremaya kilo fun oba pe yoo padanu ogun pelu omo ogun Babiloni.  Inu bi oba, o si ju Jeremaya si inu tubu, koda ninu tubu, Jeremaya si n tesiwaju lati waasu ati pe o gbagbo ninu Olorun.



Leyin igba ti o jade ninu tubu, O si tun n waasu fun Oba ati si awon eniyan lati yipada si Olorun ati pe ki won fi igbagbo won sinu Olorun nikan.

Nisinsinyi, Oba so Jeremaya si isale ogbun ti o sookun.



Sugbon Olorun wa loju ise ni ti okan Oba. O gba Jeremaya sile Ni ikoko O si beere lowo re pe kin ni Olorun fe ki Oba ko se, “Lo si igbekun iwo o si ye,” ohun ni idahun.





Omo ogun Babiloni segun Jerusalemu ati gbogbo Juda. Won bi ogiri naa wo ati gbogbo ile, won si dana sun gbogbo re. Olorun so fun awon eniyan re pe won yoo lo si igbekun fun aadorin odun, oun o si mu won pada wa si ile ileri.

# Jeremaya, Okunrin Elekun

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Iwe Woli Jeremaya

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo! Johannu ori keta ese kerindinlogun.